kori. Sise imora pelu okuta, ewe, igi, ekisa aso ati beebee lo ni a pe ni: isitjmaar-ti imora pelu omi nje: istinjaa. Ako gbodo lo eegun eran tabi igbonse (igbe) lile, lati fi se imora nitori eri ti o wa lori sise ni eewo, gege bi a se maa ri ninu awon oro ti o nbo won yii:

1. **Ako gbodo lo eegun tabi igbe lile (ti o ti gan),** eto Anobi so wipe-ki ike ati ola Allah o ma aba-**(E yee maa se imora pelu igbe lile tabi awon eegun, nitori pe eegun je ounje fun awon omo iya yin ninu awon Alujonnu)**

1. **Ki a ma fi owo otun wa gba oju ara wa mu tabi fi fo o (tamba) nitori oro re ti o so bayi ki enikookan yin ma se maa fi owo otun re gba nkan omokunrin re mu nigba ti o ba nto, ki o ma si se fi owow otun re fo egbin.**
2. **Ki a lo onka ti eeji o le pin (bi 3-5-7) lati fi se imora (bi okuta, aso, ewe, pako…)** nitori egbawa lati odo salman: **(Ojise Allah-ki ike ati ola Allah o ma aba-ko fun wa ki a maa doju ko Qibla (ibudojuko kirun) nigba ti a ban se igbonse tabi to, tabi ki a maa fi owo otun wa se imora, tabi ki o lo onka ti o kere si meta, tabi ki a lo eegun tabi igbe lile).**
   Ohun ti won fe ki a se leyin ti aba se igbonse tan ti a fe jade lati nu ile igbonse niyi;
3. **Ki o gbe ese otun re jade lati aaye egbin saaju ese otun re,** gegebi Anobi ti maa nse.

**Ki o wa se adura yi leyin ti o ba ti jade (o forijin re Allah).**

## Reference


1. Q2: 222
2. Hadith ti won panupo le lori Bukhari 135 ati Muslim :225
3. Wo iwe (minhaajul-muslim) ti shaykh Abu Bakr jabir Al-jazzaair) pg. 145.
4. Abu Dawud ati Tirmidhi
5. Tirmidhi: O sope hadith ti o ni alaafia ni.
6. Hadith ti o ni alaafia lati inu Tirmidhi 2/503 ati iba Maajah (297)
7. Wo inu iwe Akhtaohul-musoleen Pg (9)
8. Hadith tio ni alaafia ti a mu jade lati inu Abu Dawud (2) ati Ibu Maajah (335)
9. Hadith ti o ni alaafia ti a mu jade lati inu Muslim (342) ati Abu Dawud (2459) ati Ibu Maajah (340) ati Ahmad (304/1)
10. Wo inu iwe Akhtoohul -Musoleen Pg. (9-10).
11. Bukhari ati Muslim panupo lori nini alaafia re.
12. Abu Dawud ati Tirmidhi, egbawa ti o ni alafia



**Dar-ul-Arqam Communication & Dawah**
fb:darularqam.com
Whatsapp group
(08140874031, 08039193444, 08039303970, 07032553880, 08159097641, 07063060786


**Fun ibeere, imoran tabi ibeere fun awon iwe miran ti a ti gbe jade, e pe awon ero ibanisoro ti o wa loke.**

**Alaye lori:**

# IMORA SISE SIWAJU KI ATO KIRUN

*Lati Owo:*


DAR-UL-ARQAM COMMUNICATION



*Ile-Ise ti o n te iwe yi jade ni:*
DAR-UL-ARQAM COMMUNICATION
*08140874031*
*08076082440*

**ALAYE LORI IMORA SISE SIWAJU KI ATO KIRUN**

(Allah ti ola re ga julo se irun kiki ni oranyan fun gbogbo olugbagbo ododo, o sise imora ni majemu kan ti yio je ki irun je itewogba. Allah ti ola re ga julo so wipe. **(...dajudaju olohun feran awon ti o ronupiwada, o si feran awon ti o mo)**[1]. Ojise Allah ki ike Allah o ma ba so wipe **(won o ni gba irun eniti o ba ni egbin lara titi ti yio fi se alawula)**[2]. Ni idi eyi ki irun to le di itewogba eniti o fe kirun yio koko se imora. Imora yi ki se aluwala (wudhu) tabi imora gbogbo ara (Ghusl) tabi imora elerupe (tayammum) nikan. Awon eko miran wa ti opolopo musulumi o mo rara tabi ti won o ka si. Ninu awon oro ti o hun bo wa yi ni a o ti so awon eko to ro mo imora ninu esin pelu awon eri ti o fi sise re rin le lati odo Anobi Mohammed (ki ike ati ola Allah o maa ba).

**Eko ti o romo bi ase nwo aaye egbin**[3]

1. **Wiwa aaye ti o pamo tabi jinna si awon eniyan** ti o n wo nigba ti a ba fe se igbonse (egbin-ito tabi igbe). Nitori hadith anobi ti o so wipe: dajudaju **(ni igba ti anobi ba fe se igbonse yi o lo si aaye ti o pamo titi ti enkan kan ko fi ni ri)**[4].
2. **Ko ni mu wo aaye egbin gbogbo nkan ti oruko Allah bati wa lara re,** ninu egbawa isesi Anobi: **(o ma nwo oruka ti won ko "Muhammed rasul Allah" si, o je eniti o ma n bo oruka yi ti yio si fi kale saaju ki o to wo aaye egbin)**[5].
3. **Yio wo aaye egbin pelu ese alaafia (ese osi) re,** yio wa sope **(bisimillahi inni a uudhu bika minal khubthi wal khabaaithi.** Itumo – Ni oruko Allah mo n fi o wa iso kuro nibi aburu alujanu ako ati abo). Gegebi Bukhari se gbawa pe Anobi a maa so bee.
[Opolopo awon eniyan lo ti gbe Sunnah yi ju sile, sise adura yi je odi iso fun musulumi nitoripe aaye egbin je ile awon alujannu, won si le se eniyan ni suta pelu iyonda Allah ti eniyan o ba wa isora won pelu oruko Allah. Shaykh Muhammed Siddiq Al-Minthawiy – sope: Awon asise ti awon eniyan ma n se ti ko si iyapa enu lori re-lodo awon alfa esin. **Gbigbe iranti Allah ju sile nigba ti a ba fe wole egbin ati nigba ti a ba fe jade lati inure:** eleyi je asise ti opolopo awon eniyan ninu awon Musulumi ko si, ninu awon okunfa eyi ni bibori shaytan lori okan awon eniyan ati royiroyi, eyi ti o ba okan die ninu awon eniyan, iranti Allah nigba ti a aba fe wo aaye egbin wa ni ojuona meji.
**Alakoko**: **Iwa iso**, nitori oro Anas (ki Allah yonu si): Anobi (ki ike ati ola Allah o ma aba) nigba ti o ba fe wo aaye egbin, yio so wipe: **(Ire Allah mo nfi o wa iso kuro nibi aburu alujannu ako ati abo).**
**Eleekeji**: **Sise Bismillahi** nitori oro Anobi ti o so pe: **(Eyi ti yio ma je gaga (Iso) laarin Alujannu ati awon ihoho omo Anobi Adam nigba ti o ba wo aaye egbin ni ki no so pe: Bisimillahi ni oruko Allah)**[6]. Eyi yio ma waye ni igba ti o ba fe wo aaye egbin ati igba ti o ba fe bo aso lati se igbonse-nibi ni oro shaykh pari si.[7]
4. **Kii ka aso re soke titi ti yio fi bere mole daada** bo ihoho re ti islam pa ase re.
Shaykh Muhammed Sidiqqi Al-Minthiaawiyi **(Gbigbe jusile imo bo ihoho ara nigba tiwon ba fe se igbonse:** opolopo eniyan ni o maa nse isise lati ma abo ihoho won nigba ti won ba fe se igbonse, to fi je wipe apakan ninu awon ti won n koja lo yio maa ri ihoho re, sugbon ninu ilana re (Anobi-ki Alafia Allah o ma aba) nigba ti o ba fe se igbonse, yio lo sibi ti o pamo, won o si ni gbo iho( ariwo tabi didun, igbonse re). won o si ni gbo oorun re.
Lati odo Jaabir (ki Allah o bawa ke) o sope: **(A jade pelu Anobi lori irin ajo, ti o ba fe se igbonse yio lo aaye ti o pamo ti eni kankan o sin ni ri)**[8]. Lati odo Abdullah iba Ja'far (ki Allah o bawa ke oun ati baba re) o sope: **(Ohun ti Anobi nife si julo lati maa fi di gaga ihoho re nigba ti o ba fe se igbonse ni: ibi ti o ba ga dada lori le, ati igi dabinu**[9]**)**.[10]
5. Kii bere nigbati o ba fe se igbonse tabi to ni eniti yio koju si qibla tabi ko eyin si. Nitori oro re ti o sope: (ki ike Allah o maa ba).

**(E ye maa doju tabi keyin si Qibla nigba ti eba nse igbonse tabi to)**[11].

6. **O tun ko bakan naa ki a maa se igbonse egbin tabi ito si booji awon eniyan (ibi ti awon eniyan ti n gba afefe)** tabi ni oju ona won tabi nibi ti won ti n pon omi tabi ni abe igi ti o ni eso. Nitori oro Anobi ti o so pe: **(E sora fun aaye igbeni sepe (ti eniyan ba se egbin sibe) meta: sise egbin si aaye ti awon eniyan ti n pon omi ati aarin gbungbun ona ati abe booji)** bakan naa ni hadith wa lori kiko fun ni lati maa se egbin si abe igi ti o ni eso.
7. **O ko ki a maa soro ni ori egbin,** nitori oro re ti o sope-ki ike ati ola Allah ki o maa ba **- (ti eniyan meji ba nse egbin ki won o ya fi gaga si aarin won, ki won ma sise ba arawon soro (Lori egbin) dajudaju Allah korira eyi).**

**#Awon nkan ti a fe fun eni ti o fe tamba (mora kuro nibi egbin ito tabi igbe) pelu omi tabi nkan miran ti o le ropo re#**

Gegebi ofin esin Islam se pawa lase ki a se imora pelu iyepe nigbati aba wa omi ti a ko ri tabi ti a ko ni ikapa lati lo, bee naa ni tun se ni ofin fun wa lati lo awon nkan ti a le fi mo kuro nibi egbin igbonse tabi ito ni gba ti a ba wa omi ti a